# ALHAJI ǪNASANYA DI BALOGUN IJEBU-ODE


# IROHIN YORUBA

Ẹṣin Oro Wa— " IWAJU L'ǪPA ẸBITI NRE SI "


**Akiyesi**

Ti ẹ ba nkowe si wa ki ẹ ma ṣe kọ ọyanju, ki a le tete ma a tọ ẹ jade fun nyin, eyiti ko ba yanju dele kole jade rara. Nitorina a tun tọ ẹ mọ nyin leti daradara "Ẹ ma a kọ iwe nyin yanju o"

Olotu

## OLOYE ADEYEMǪ ALAKIJA GBA MEDALI OYE : £800 NI OWO MAYOR EKO


IV VOL, NO, 464 IBADAN, MONDAY, MAY 7, 1951, OWO IWE IROHIN YORUBA — KǪBǪ KAN (1d)




**Major M. N. Hennesy**
Ni ẹniti nwọn ṣẹṣẹ yan si ipo Assistant Public Relations Officer (Marketing)

## Alhaji Ǫnasanya Di Balogun

IJẸBU-ODE—Ni aṣalẹ Ọjọbọ ti iṣe ọjọ kerindinlọgbọn oṣu to kọja yi ni Ọba Alaiyeluwa Gbelegbua keji C.M.G., C.B.E. Awujalẹ Ijẹbu Ode kede rẹ si eti gbogbo enia lati inu Afin rẹ pe Alhaji Fasusi Adeṣoye Ọnasanya di Balogun Ijẹbu-Ode dipo Oloye Ologbe Kuku ti o ṣe alaisi ni ọdun ti o kọja yi. Alhaji yi jẹ ẹniti nfi mọto papọ ṣowo, o si jẹ enia ti o gbajumọ, o si tu lawọ.

Ikede ti Ọba ṣe yi jẹ ayoriṣiwadi Igbimọ ti awọn Oloye wonyi: Agbọn, Apena, Olufọrẹ, Apẹna ati Lapoẹkun, Oloye Y. L. Kukọ yi ni o si ṣe Alaga Igbimọ Oluwadi na, nitoripe awọn enia mẹta ni o ndu Oye na. ṣugbọn nigbati awọn Igbimọ na fi ara balẹ yẹ ọrọ na wo, nwọn ri i wipe Alhaji Onasanya ni o tọsi ju awọn yoku lọ, ni nwọn ba lọ jẹ abọ fun Ọba.

Ọba si ṣe arọwa fun awọn meji yoku ti Oye na ko bọ si lọwọ, ati awọn alatilẹhin wọn pe ki nwọn maṣe binu ati pe ki nwọn ma ṣe ditẹ si ẹniti Oye na bọdi si lọwọ. nitorina ki nwọn lọ papọ pẹlu rẹ lati ba a ṣe Aṣeye Oye titun na.

(Wo oju ewe kẹrin)

ẸGBẸ-TEMIDIRE ATI ẸGBẸ AMULUDUN PAPỌ

ODO-ERI—Eyi jẹ idagbasoke ire ilu wa lati ri i pe Ẹgbẹ-Temidire ati Ẹgbẹ Amuludun papọ lati ọjọ 'Ru ti iṣe ọjọ kejidinlọgbọn oṣu keji ọdun yi (28/2/51) Lati igbayi lọ ni orukọ wọn ti di Ẹgbẹ-Temidire ati Ẹgbẹ Amuludun Company.

Gẹgẹ bi o ti wu Ọlọrun lati mu irẹpọ wa ni arin awọn Ẹgbẹ mejeji yi ati lati pa wọn pọ fi ṣe ọkan, adura wa ni pe ki Oluwa jẹki idapọ wọn na ṣe ọpọlọpọ ire fun ilu wọn.

Amọran wa fun awọn ẹgbẹ yi ni pe ki nwọn maṣe fi eti si ọrọ awọn ẹlẹgan, nitoripe awọn pẹganpẹgan wa lati ba ile aiye jẹ ni "awọn baba wa si ti ri wọn tan ki nwọn to ma a powe pe "Aṣọ pẹganpẹgan ki i pe meji penpe ni aṣọ ẹṣinṣin mọ."

Ẹ maṣe f'eti si ti awọn Agbọyisọyi enia, ẹ ma jẹki awọn ẹlẹtan o ri nyin gbe ṣe. Oluwa yio mu ẹsẹ awọn Ẹgbẹ na duro ṣinṣin. Ha! Iru ifẹ bayi wu wa o, Ajumọṣepọ ni o dara o, apapọ ọwọ ni a fi nsọ aiya. A si tun yọ fun Ọgbẹni A. Adegboye ati gbogbo

(Wo oju ewe kẹrin)

## £800 Ni Owo Mayor Eko

EKO—Ninu ipade ti awọn Igbimọ Munisipa Eko ṣe ni ọjọ Iṣẹgun ti iṣe ọjọ kini oṣu yi ni Akọwe Igbimọ na ka iwe Ọlọla Gomina fun awọn Igbimọ na pe Ẹgbẹrin pọnun (£800) ni on ati Igbimọ on ri pe o tọ fun Mayor Eko lati ma a gba lọdọdun.

Tẹlẹtẹlẹ ri Ẹgbatala pọnun o din ogorun (£2,500) ni awọn Igbimọ Munisipa ti taku si pe Mayor ni lati maa gba lọdọdun ṣugbọn Gomina ati Igbimọ rẹ ri i pe o pọju, ni nwọn ba mari rẹ si apo mẹjọ yi.



**Ọgbẹni A. E. T. Benson**
Ni Aṣoju Ijọba (Chief Secretary to the Government) Nigeria titun ti o ba ọkọ "Apapa" de si ilẹ yi ni ọjọ 'Ru ti iṣe ọjọ keji oṣu yi, lati dipo aye Aṣoju Ijọba ti Ọgbẹni H. M. Foot fi silẹ nigbati o nlọ jẹ Oye Gomina Jamaika.



**Ọlọla Oloye Adeyemo Alakija K.B.E.**
On ni o gba mẹdali oye ti Balẹ awọn Labanese (Kọra) fi da a lọla

## Oloye Alakija Gba Medali

EKO-Ni ọjọ Iṣẹgun ti iṣe ọjọ kerinlelogun oṣu to kọja yi ni Ọgbẹni Hasnn Osseiran ti iṣe Olori gbogbo awọn Lebanese (Kọra) ilẹ yi pe gbogbo awọn Oloye ati Ọlọla ilu yi jọ ni ile rẹ 6 Mayẹ Street Yaba fun aṣeyẹ nipa fifi mẹdali Oye ti Balẹ ilu wọn fi sọwọ fun Ọgbẹni Ọlọla Adeyemọ Alakija K.B.E. fun un.

Nigbati Ọlọla Oloye ati Iyalfin Adeyẹmọ Alakija fi gba atẹgun lọ si ilu Oyinbo ninu ọdun 1949 ti nwọn si lọ bẹ ilu Lebanon (ilu awọn Kọra) wo ni Balẹ ati gbogbo awọn Ọlọla ilu wọn ba fi gba wọn towọ-tẹsẹ ti nwọn si ṣe aṣeyẹ pataki fun wọn lọhun.

Lẹhin eyi ni Balẹ na wa a fi oye ilu wọn da Ọlọla Alakija lọla fun ifẹ ajumọṣe-papọ ti o wa ni arin awọn Kọra ti o wa ni ilẹ yi ati awa ara ilẹ yi, mẹdali Oye na ni Olori awọn Kọra ilẹ yi na wa a fi jiṣẹ fun Ọlọla Alakija lojo gbogbo awọn ti o pe sibẹ yi.

Ọdun (300) enia ni o wa sibi aṣeyẹ yi ṣugbọn awọn diẹ ti aye

(Wo oju ewe kẹrin)

